| ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU<br>Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.<br>ÈTÒ IPÀDÉ AGBÁRA GBỌDỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́ |
|---|
| Ó TÓ GẸ́Ẹ́<br>OṢÙ KỌKÀNLÁ, ỌDÚN 2024<br>Ìwé Mímọ́ Kíkà: 1 Sámúẹ́lì 17<br>Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 138:8 |

ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti ìtẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Májẹ̀mú òkùnkùn ìyówù pẹ̀lú ìlú tí a ti bí mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára Íkábódù lórí ayànmọ́ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo iṣòro tó ndá ògo mi lóró, kú, ní orúkọ Jésù.
8. Ẹsẹ̀ mi, kọ ìpadàsẹ́yìn, ní orúkọ Jésù.
9. Ògo ayé mi tí wọ́n ti jílọ nínú oyún, mo gbà ọ́ padà nípa iná, ní orúkọ Jésù.
10. Olùkó àyídáyidà bá ògo àti adigunjalè ògo ilé bàbá mi, jẹ́ kí nlọ, kú báyìí, ní orúkọ Jésù.
11. Ònfà a fa àjàgà mọ́ra, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, já ìdè rẹ lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.

12. Àwọn ọjọ́ mi kò ní wà láìnísinmi, ṣùgbọ́n a ó pè wọ́n ní àwọn ọjọ́ Olúwa, ní orúkọ Jésù.
13. Ohunrere ìyówù tí ó ti dòkú nínú ayé mi nígbà tí mo jẹ́ aláìmọ̀kan, gba ìyè báyìí, ní orúkọ Jésù.
14. “Èmi Ni Tí Njẹ́ Èmi Ni”, dìde, ṣàfihàn agbára Rẹ nínú ayé mi, kí O sì múmi lọ sí ìpele mi tó kàn, ní orúkọ Jésù.
15. Olúwa, mo so ayànmọ́ mi sínú orísun agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti gba ìgbédìde atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, mo so ayé mi sínú orísun agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti gba ìtẹ̀síwájú atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
17. Mo gun ẹṣin ogun, mo sì gún lọ sínú ilẹ̀ alàjá, orúkọ Jésù.
18. Oòlù Ọlọ́run, fọ́ gbogbo ẹsẹ̀ ibi tó n rìn lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
19. Gbẹ́nà-gbẹ́nà ọ̀run, kan gbogbo adigunjalè t'ẹ̀mí tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi pa, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo ẹ̀mí búburú nínú afẹ́fẹ́, tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìpele mi tó kàn, túká sí ìdahoro, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ẹ̀mí búburú nínú ẹ̀fúùfú, tó n ṣe ìdíwọ́ sí ìrìn ìlọsíwájú mi, túkà sí ìdahoro, ní orúkọ Jésù.
22. Gbogbo ẹ̀mí búburú nínú omi, tó n dènà ìgbésẹ̀ mi láti lọ sí Ilẹ̀ Ìlérí mi, túká, ní orúkọ Jésù.
23. Gbogbo ipá sàtánì tí wọ́n yàn lòdì sí ògo mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
24. Gbogbo òfin sátánì tí wọ́n ṣètò lòdì sí ìràwọ̀ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo òfin ìrandíran tí wọ́n ṣètò sínú ọ̀run lòdì sí ayànmọ́ mi, kú, ní orúkọ Jésù.

26. Ọlọ́run dìde, lo gbogbo ohun ìjà tí mbẹ ní ìkáwọ́ Rẹ láti dójútì àwọn ọ̀tá ìpele mi tó kàn, ní orúkọ Jésù.
27. Gbogbo èrò àti ibi tí wọ́n ṣètò lòdì sí ayé mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo èdìdì ìrandíran ibi lórí ayànmọ́ mi, mo fọ́ ọ, mó sì yọ ọ́ dànù, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo ẹ̀jẹ́ sátánì lòdì sí ayànmọ́ mi, fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo ẹbọ sátánì tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
31. Gbogbo àsopọ̀ àìmọ̀ pẹ̀lú àwọn wòlíì àti àwọn aríran èké, fọ́, ní orúkọ Jésù.
32. Ibùgbé mi, kí odi ẹ̀gún yí ọ po, ní orúkọ Jésù.
33. Ibùgbé mi, kí odi iná yí ọ po, ní orúkọ Jésù.
34. Mo gbédè gbogbo ẹ̀mí ìdè pẹ̀lú ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ àti ẹ̀wọ̀n irin, ní orúkọ Jésù.
35. Ẹ̀yin ọ̀tá ilé bàbá mi, mo kọ̀ kí ẹ ṣiṣẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogbo òfin tí àwọn agbára òkùnkùn ṣe lòdì sí mi, mo fagile yín, mo sì sọ yín di asán àti òfo, ní orúkọ Jésù.
37. Mo ba ifẹ́ ọ̀tá jẹ́ lórí gbogbo agbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.
38. Mo mú àjínde Jésù Krístì Olúwa, lòdì sí gbogbo agbára òkùnkùn tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
39. Ẹ̀mí Mímọ́, jà lòdì sí àwọn tó n jà lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
40. Olúwa, jẹ́ kí àwọn agbára ìkà ilé bàbá mi gba idààmú, kí a sì dójútì wọ́n, ní orúkọ Jésù.